# LẸHIN IKU ... KINI?



## LẸHIN IKU . . . . . KINI?

"Onisegun, kini ohun ti o mọ nipa ọjọ ọla? Kini ohun ti o wa lẹhin iku? Njẹ ohun miran tun wa lẹhin iboji? Ki o to di akoko yi awọn ibeere wọnyi ki i jọ mi loju, nwọn ki i tilẹ wa si ọkan mi, sugbọn ni lọọlọ yi ni mo wa bẹrẹ si ronu lori awọn ibeere wọnyi, awọn ibeere naa si ndaamu mi gidigidi."

Onimọijinle ninu ede Heberu ti arakunrin yi doju ibeere rẹ kọ, dahun wipe: "ah, awọn ohun ti o beere wọnyi jẹ awọn ohun ti a ko le mọ ohunkohun nipa rẹ. Ohun ti o se pataki ti enia le se ni wipe, ki o maa gbe igbesi aiye ti o rọrun fun u julọ, ki o si jẹ ki eleyi ki o to oun.

Njẹ onimoijinle yi tọna bi? Njẹ a le mọ awọn ohun ti o nbọ wa sẹlẹ lẹhin iku?

Bibeli sọ fun wa wipe: "ninu ọgbọn, aiye ko mọ Ọlọrun" (1 Korinti 1:21). A ko le mọ Ọlọrun nipa ọgbọn aiye, bakanna ni a ko le fi ọgbọn ori enia lasan mọ ọjọ iwaju. Ọlọrun nikansoso ni O mọ ọjọ iwaju, Oun nikan naa ni O le fihan funwa, O si ti fi i han fun wa ninu ọrọ rẹ, Bibeli.

Bibeli fi awọn otitọ kan ti o dẹrubani han wa. "A ti fi lelẹ fun gbogbo enia lati ku lẹẹkansoso, sugbọn lẹhin eyi, idajọ" (Heberu 9:27). Nitorinaa, iku kọ ni opin ohun gbogbo. Iku ko tumọ si iparun patapata, tabi imukuro, bẹẹni ko si tumọ si orun-ẹmi. Bibeli tun sọ wipe, gbogbo awọn oku ti o wa ninu isa-oku ni yi o gbọ ohun Ọmọ Ọlọrun, ti nwọn yi o si dide, yala si ajinde iye ainipẹkun tabi si ajinde iya ailopin (Wo Johannu 5:28, 29).

Aworan ajinde si idajọ ni a fi han wa ninu iwe Ifihan 20:11-15. Nibẹ ni a ti kọ ọ wipe awọn oku yi o jade wa lati inu isa-oku, nwọn yi o si duro niwaju itẹ nla funfun, a o si se idajọ wọn gẹgẹbi ohun ti a ti kọ sinu iwe kan nibiti Ọlọrun ti kọ awọn ẹsẹ wọn si. Ẹnikeni ti a ko ba si ri orukọ rẹ ninu iwe iye, a sọọ sinu adagun ina. Eleyi ni iku keji.

Sugbọn Ọlọrun tun ti fi han ninu ọrọ Rẹ wipe, iku Jesu Kristi nikan ni ọna ti ẹlẹsẹ le gba de ọdọ Oun. Gbogbo awọn ti o ba tọ Ọlọrun wa, nipa igbagbọ ninu Oluwa Jesu Kristi gẹgẹbi Olugbala, ti kọja lati inu iku bọ si iye. "Lootọ, lootọ ni Mo wi fun nyin, Ẹnikẹni . . . ti o ba gba Ẹniti O ran Mi gbọ, o ni iye ti ko nipẹkun, oun ki yio si wa si idajọ, sugbọn o ti re iku kọja bọ si iye" (Johannu 5:24).

Sise ojuse wa, tabi gbigbe igbe-aiye ti o dara loju ara wa, ati riro wipe ọjọ iwaju yio se itọju ara rẹ, ki ise ọna Ọlọrun fun igbala. Oluwa Jesu Kristi sọ wipe: "Bikosepe ẹnyin ronupiwada, gbogbo nyin ni yio segbe bẹẹ gẹgẹ" (Luku 13:3). "Bikosepe ẹ ba gbagbọ pe: Emi ni, ẹ o ku ninu ẹsẹ nyin" (Johannu 8:24).

Iru iha ti o ba kọ si Jesu Kristi nihinyi ati nisisiyi ni yio sọ bi ọjọ iwaju rẹ yio ti ri. Bi iwọ ba ronupiwada ti o si gba A pẹlu igbagbọ

gęgębi Olugbala rę, iwọ yio ni iye ainipękun. Sugbọn, bi o ba kọ, a o sọ ọ sinu adagun ina. Tani o sọ bẹẹ? Ọlọrun ni o sọ bẹẹ. Mase ni ero wipe ohun gbogbo yio yipada si daradara lęhin igbati o ti yi ęhin rę pada si I.

"Asaalę oni lee ję arikęhin fun ọ
Akoko rẹ diẹ nihin yio si kọja lọ,
Egbe aiyeraiye — iku keji —
Duro de gbogbo awon a-kọ-Kristi-silę.
Iwọ yio si ri opin bụburu rẹ!
Akoko kọja lọ, lęhinna a — AIYERAIYE!"

"Ọlọrun fẹ araiye tobęę gę, ti O fi Ọmọ bibi Rẹ kansoso fun ni, ki ęnikęni ti o ba gba A gbọ ma ba segbe, sugbọn ki o le ni iye ainipękun" (Johannu 3:16).

**Word Of Truth**, P.O. Box 1126, Kaduna, Nigeria